# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL. I. NO. 52. SATURDAY, JULY 7, 1923. FOURPENCE.

ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Opopo nla lẹmẹta lọsẹ. Awõ-ṣẹju ni awọn aworan rẹ. Ina Manamana ti a si fi nṣe Ẹrọ na mọlẹ bi ọsangangan. Ọrẹ, lọ fi onjẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday, Wednesday* ati *Saturday*, ni agogo mẹjọ abọ alẹ (*8.30 p.m.*)

## A. KESSLER,

ILE OWO OYINBO GERMAN HAMBURG

Iwọ le ranṣẹ Ẹrọ-Iranṣọ "*Mundlos*" ati "*Adler*" nibẹ bẹ si ni Ẹrọ-riran bata pẹlu.

Ẹ tọ Ọgbẹni A. Kessler lọ ni 7 Labinjo Lane, kọrọ Williams Street.

CHIEF SECRETARY'S OFFICE
10 JUL 1923



MUNDLOS



A nranṣẹ orisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*

Ọja tiwa ya. A si ni ọja wọnyi fun tita.—Ohun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kẹkẹ-ologere t'Ọkunrin t'Obinrin, Waji.

Ẹ le ri Ẹrọ Iranṣọ "*Mundlos*" ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati lọdọ H. Campos ti Campbell Street.

**Mundlos on top Mundlos.**

**Mundlos on top Mundlos.**

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun sikolẹ fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ẹbun titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na 'jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ 9.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni
No. 41 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Paun ikọle, Aṣọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Satten.*)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra li nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, E LỌRAN.
AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to sẹşẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Măse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

### "EKO AKETE" D'ỌMỌ ỌDUN KAN.

Loni Iwe-Irohin wa "Eko Akete" di ọdun kan ti a ti bẹrẹ rẹ a si dupẹ lọwọ awọn ọrẹ ati ojulumọ wa ti nwọn ṣe iranwọ fun ni lorişirişi ọna ti nwọn ko jẹ ki "Agbo" pa "Ọmọtitun" na lori, nigbati o wa ni "ẹjẹ ọrun." A tọrọ Ibukun at'oke wa si ori awọn olore wa wọnyi, a si ni ireti pe nwọn ki yio dẹkun ati ma gbe ọwọ wa soke ninu iṣẹ nla yi fun anfani, rere, ati itẹsiwaju awọn enia wa nibi gbogbo.

### ỌDỌMỌDE KO L'AIYA AKẸBỌJẸ!!

Ni iwọn agogo mẹwa arọ ọsẹ tokọja ni Oke Arin, a gbọ pe ija da ọmọde-kọnrin kan ati ọkọnrin ara oke kan pọ nipa gbigba *ball* tobẹ to fi jẹ pe ọmọde kekere na ti a sọ pe o jẹ ọmọ ile Ọgbẹni Abina ni ita Balogun, fi fa igbanu (*belt*) yọ to si fi na ara oke na, ti igbanu na fi ba a ni atari lọgan ẹjẹ ntu pupu, ki a to ṣẹju ẹ a gbọ pe ọmọ ara oke na ti d'oku!!! Wara-were ọmọde yi fi ere si i ṣugbọn laipẹ awọn enia ra a mu o si wa ni itimọle nisisiyi laisi ani-ani ẹjọ ọdaran ọmọ na yio di "Ganran" (*Criminal Assizes*) ti a ṣe nibi ni oṣu to mbọ; a gbọ pẹ alagbafọ ni ọmọ ara-oke na nṣe to y... sọun ọsan gangan bayi!

### IJỌ BROTHERHOOD D'ARABA.

Gẹgẹ bi a ti sọ lati iwọn bi ọsẹ meji sẹhin, "igbo-akan-mọ-pa" ni ẹyẹ ti awọn Ijọ yi ṣe fun Alufa wọn *Pastor* Adeniran Adedeji Iṣọla ni ọsẹ yi lati ọjọ *Sunday* t'okọja titi fi di ana ti nwọn p'agbo ijọ ti ilẹ wa ni Ilupesi, eyi ti a fi pari Ajọyọ na: laipẹ Irohin kikun mbọ ti olukuluku yio fi le gbadun bi a ti ṣe ẹyẹ na si.

### Ẹ KU, AJAGUNMOLU!

A ba awọn ara wa awọn Ọgbẹni Withnel Majarọ Williams (*Kuli Boy*) Charles Ọbafẹmi, ati A. O. Delọ Dosunmu B.A., L.L.B., (*Lond*) yọ fun pipe ti awọn Ọga Ofin (*Benchers*) pe wọn si iṣẹ *Lawyer* ni Ilu Oyinbo ni ọjọ kẹtala oṣu *June* to kọja; a ro pe laipẹ nwọn yio bọ wa'le.

### SARA RẸ NIYI, IBIDUNNI ADU-MADAN.

Bẹ si ni a ba ọrẹ wa Ọgbẹni L. Ibidunni Agusto yọ fun yiyege to yege Idanwo ikẹhin to ṣe lati ma ṣe iṣẹ *Lawyer*, gẹgẹ bi a ti rika ninu Iwe Irohin *West Africa* ni lọlọyi. On pẹlu ko ni pẹ de sibi, ti o ba de on ni yio jẹ Imale kinni ni iha Iwọ Orun Afrika (*British West Africa*) ti Gẹsi ti o kọ gba Iṣẹ *Lawyer* larin wa nibi. A ba awọn ọrẹ wa ti *Ahmadia* yọ fun orire olori wọn yi ti o kọ fi idi Isin na lelẹ nibi ni ọdun diẹ sẹhin.

### ARA FẸ JOJO.

A ki Ọgbẹni D. Ayọdele Bright O dabọ fun Isinmi ọse diẹ (*Leave*) to gba lati jẹ fãji lọ sile Ifẹ pẹlu Obinrin ati awọn ọmọ rẹ. Ọgbẹni na jẹ Aka-iwe titẹ (*Proof Reader*) ni Ibi'ṣẹ Ile Itẹ'we ti *Railway* ni Ebute Mẹta.

### BABA TOTO BABA, O KU INAWO!!!

A dupẹ gidigidi lọwọ *Bishop* Oluwọle fun pọnun mẹdogun (£15) to fun gbogbo awọn ọmọ ile'we ti o lọ ki ni lọlọyi, nigbati a nṣe ajọyọ ọgbọn ọdun to ti wa ninu oye *Bishop* na; Ẹ ṣe, A-na'wo-bi-ẹlẹda.

## KABỌ, ỌKUNRIN KOKO-BỌTỌ.

A ki Ọgbẹni E. Marcus Thomas ti Ita Taiwo l'Eko kabọ lati *Zaria* nibiti o ti lọ fun ọpọlọpọ ọdun fun iṣẹ. Onigbanjo ni Ọgbẹni na nṣe lọhun ko to dakan wa'le. Abọ o!

## ỌMỌ ADARAMAJA O KU ORI'RE.

A ba Alufa S. A. Pearse yọ fun ori're to ni nipa titiraka ti awọn Ero *Church* rẹ (Ọbun Eko) tiraka lati gba Ina manamana (*Electric Light*) si *Church* wọn, eyiti wọn tan ni alẹ ana; A ki Ẹnyin *Member* ati Alufa ku'ṣẹ. O yẹ nyin o!

---

## "NIPA ESO WỌN LI ẸNYIN O FI MỌ WỌN."

Emi ki yio ni itẹlọrun lati dakẹ niwọn igbati Oyenẹyẹ ko ba dẹkun ati ma sọ isọkusọ.

Ni Page 5 "Eko Akete" ti June 23. Oyenẹyẹ yka si awọn orin meji pataki ti o ro pe ọrọ wọn yọ inu ara wọn; nipa ti awọn orin kini ti o tọka si, emi ki yio sọ nkankan nipa iwọnyen, ṣugbọn eyiti emi yio sọrọ nipa rẹ ni awọn orin keji ti o tọka si, awọn orin na ka bayi:—

### I.

1. Ta lo lawa o ni Baba,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ!
   Ọba Oluwa ni baba wa,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ.

2. Ta lo lawa o l' amọna,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ!
   Jesu Oluwa l' amọna,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ.

3. Ara ẹ jẹ ka jọ yọ,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ!
   Fun 'dariji ẹṣẹ wa,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ.

4. Ọpẹ l' o yẹ fun Jesu,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ!
   Fun 'ṣẹ nla t' O ṣe fun wa,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ.

5. F' iyin f' Ọlọrun Baba,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ!
   F' ọmọ at' Ẹmi Mimọ,
   Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ. *Aṣ.*

### II.

1. Tani p' awa o m' Ọlọrun?
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ.
   Ọlọrun l' Ẹlẹda wa,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ;
   Orere o! Orere o!! (2)

2. Tani p' awa o gba Jesu?
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ.
   Jesu l' Olugbala wa,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ;
   Orere o! &c.,

3. Tani nko tiwa kuro?
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ.
   Tiwa l' olubori o,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ;
   Orere o! &c.,

4. Ọṣẹsin, tun 'wa nyin ṣe,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ.
   Gẹgẹ b' aperẹ Jesu,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ;
   Orere o! &c.,

5. K' Ọlọrun Ẹlẹda wa,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ.
   F' iṣẹgun fun gbogbo wa,
   Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ:
   Orere o! Orere o!! (2)–*Aṣ.*

Bi aiye ti jina si orun (*sun*) to, ati bi igbagbọ awọn Ijọ mejeji ti yatọ to, bẹ gẹgẹ ni awọn orin mejeji wọnyi.

Eredi ohun ti o mu orin wọnyi wa s'ẹnu awọn Ijọ mejeji?

(*a*) Ijọ kini, nitori iyapa ti o wa larin awọn ati Ijọ C.M.S. pẹlu Ijọ Wesley, nitorina awọn Ijọ Oyinbo ko gba pe Ọlọrun wa pẹlu Ijọ Ọmọ-ibilẹ ati pe Ọlọrun ni Baba wọn, nitori ede-aiyede nipa ti i-ko-birin-jọ. Ati pe bi Ọlọrun ti jẹ Baba fun Ijọ Oyinbo, be lo si jẹ Baba fun Ijọ Ibilẹ, mo si ro pe iru ero yi lo mu Ijọ Ibilẹ ṣe (*compose*) orin apa kini lọna to ba ẹkọ wọn mu.

(*b*) Ijọ keji, laiṣe ani-ani, ẹnikẹni lo mo ẹni na ti o ṣe (*compose*) orin keji; ọrọ orin na si yatọ si ekini gegẹ bi mo ti wi lakọkọ. Nigbati a da Ijọ (*Brotherhood*) yi silẹ, ariwo sọ ku-u, igbe ta gbo-o, pe a ko gbọ iru eyi ri, nitori Ijọ na ko gba ẹkọkẹko Mẹtalọkanṣọṣọ ti ki iṣe ẹkọ Jesu Amọna, to si lodi si ẹkọ Bibeli: nitori eyi, awọn Ijọ yoku gba pe nwọn ko mọ Ọlọrun, ati pe nwọn ko gba Kristi Jesu gbọ pẹlu. Eyi lo mu orin yi wa s'ẹnu ẹniti o ṣe orin na, lati fihan awọn oluyọṣuti-si-Ijo yi pe, bi nwọn ti gba Ọlọrun ati Kristi Jesu gbọ, bẹ gẹgẹ ni Ijọ (*Brotherhood*) yi gba Ọlọrun gbọ pẹlu.

Anu ṣe mi gidigidi pe iru Oyenẹyẹ kẹ, ko mọ iyatọ larin "NI" ati "MỌ"—o ma ṣe o!

O yẹ gidigidi ki ọrọ botoboto maṣe ma ti ẹnu agbalagba jade, ṣugbọn agbalagba miran wa ti ko ni itiloju rara, Oyenẹyẹ si jẹ iru agba bẹ; ẹwẹ Oyenẹyẹ tabi ẹniti o fi orukọ Oyenẹyẹ ṣe iboji (*shadow*) ati bi o ti fi ara han mi pe on ni Oyenẹyẹ ti "Eko Akete" jẹ ọkan ninu awọn Ijọ Brọdahud (*Brotherhood*) on kanna si jẹ ọkan ninu awọn Ijọ *African Bethel.* Ewo-lewo, Brọda, "*African* tabi *Brotherhood*"? Nipa eso wọn li ẹnyin o fi mọ wọn. Oyenẹyẹ kanna "*Brotherhood,*" on kanna "*African*"; sibẹsibẹ o nfi ebu awọn Ijọ mejeji to jẹ ẹyẹ wọn ṣe ayọ.

O san ki Oyenẹyẹ ma pọn omi si apẹrẹ ju obotoro yi lọ, ọjọ melo lo ma ṣe eyi gba, ki o si ma fi iwa aṣa ṣe ayọ?

"Ẹni riru ko ni le bori o" } *2 times.*
"Ẹni riru ko ni le bori" }
Iwọ nṣe 'kini, iwọ nṣe 'keji o,
O yi biri, o ns'oboto.

(*Tune:*—Iwa pẹsẹ l'Ọlọrun wa fẹ.)

A. ỌLA. AJIB.

---

## THE FIRST VOLUME.

*By Adekanbi.*

With to-day's issue *Eko Akete* is exactly one year old. This is a sufficient excuse for the appearance of these few words in print and the writer believes all readers, at least all sane readers, will not deny this valuable paper of its share of congratulations due from them.

That this paper is not the first venture of Mr. Adeoye Deniga in the local journalistic enterprise need hardly be said in view of the fact that besides being the Editor of an interesting annual *The Nigerian Who's Who*, he founded and edited *The New Age Herald* (1910) and another paper called *The Herald* (1913) (bilingual) both of which are now defunct.

Let us look as far back as one year i.e. as far back as the birth of this paper. What has it done for its increasing band of readers as well as the public in general?

The fact that a paper of this kind was a long-felt want cannot be too much emphasised and for this right step in a right direction the founder again deserves commendation.

A contemporary run exactly on the same lines with this paper has only come to prove the importance and necessity of such kind of journal in Lagos—these two papers have since been working for good and progress in the local community. Who of us regular readers of *Eko Akete* is not anxiously on the look out every Saturday for his or her own copy just to rush through one or other of its interesting columns—may be the table of *Preachers for Tomorrow, Gbohun-Gbohun* or the stylish and humorous editorial language characteristic of the paper?

Nay, it has brought to the mass of Yoruba reading or speaking people much that was hitherto unknown to them resulting in their general education, civilisation and consequent upliftment.

It has made our local English Newspapers see the necessity and benefit of devoting a section (known as Yoruba Column) to the Yoruba language.

On this and many other grounds it is to be hoped that both friends and foes would be *broad* enough to applaud the works done by *Eko Akete* and its editorial staff.

Three Cheers to Professor Deniga!

Hip!!! Hip!!!—Hurrah!!!

---

## CHILDREN'S CORNER.

### DUTIES OF CHILDREN TO THEIR PARENTS.

There are many children who speak to their parents with rudeness and grow sullen when their parents rebuke them. Beware of such disrespect. Treat your parents with respect. You are young, and you should therefore take the lowest place. You have much to learn, and you should therefore hear instead of seeking to be heard. When Solomon on his Throne, saw his mother approaching him, what has he done? He rose and bowed himself unto her, and caused a seat to be set for her on his right hand. Let this wise king be your example. Be grateful to your parents. When you could neither speak nor walk, when you were only a burden and care to them, but did they forsake you? When you were sick, how tenderly did they handle you.

You should have no secrets which you are unwilling to tell them, strive to fulfil the hopes of your parents, by growing in knowledge, by shunning bad companions.

Children, obey your parents. Do not receive their commands with a sour. Children, these are your duties. Surely there cannot be a greater monster than an ungrateful child.

Thanks Editor, for space allowed.

L. S. OKE.

---

## C.M.S. GRAMMAR SCHOOL

64th FOUNDER'S DAY 1923.

O.G.S SPORTS SECTION.

In connection with the celebrations of the 64th Founder's Day of the above School, a Football March was played between the Old and present Boys, Mr J. M. Akinloye captained the Old Boys and Mr. N. Ekpo the Present. Promptly at 5.30 p.m. Hon E. O. More kicked off thus giving signal to the two sides to set to work. Each side was keen and fought bravely to win the goal, and from the beginning and for a long time the Old hand presses the Present and promised to win the day. But the Present brought into [illegible] the activity and smartness of School Boys a[illegible] succeeded in carrying away all the four go[illegible]

The Kings College Ground where the Match was played was crowded with spectators among whom were found on invitation, the Lieutenant Governor Colonel Moorehouse and other elite of the town. The Philharmonic Band was in attendance discussing throughout melodious and exquisite pieces. Our thanks are greatly due to Hon E. O. Moore and in no less to Mr F. B. Mulford who kindly acted as Refree and Messrs G. I. Righton and E S Ikoh as Linesmen.

Those who have responded to our invitations and contributed by their presence to the success of the occasion deserve our praise.

GEO. I. PHILLIPS
*( Hon. Sec. Sports Section )*

---

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, JULY 7, 1923.

---

## BI ERE BI ERE, ALABỌRUN D'ẸWU. AJỌDUN WA EKINNI.

*Saturday* osẹ oni lojẹ ọsẹ mejileladọta ti nṣe ọdun kan gbako ti a ti bẹrẹ si Iwe-Irohin yi lọsọsẹ; gẹgẹ bi ode ko ti jẹun tobẹ nigbana nipa ti owo ti o ṣọwọn nilu pẹlu ominu-furu ẹdọ-furu ni a fi bẹrẹ a si dupẹ lọdọ awọn ọpọlọpọ Bọkinni Ilu wa yi, ti nwọn jẹ ọhẹn nipa iranwọ aile f'ẹnu sọ ti nwọn ti ṣe fun ni lorişirişi ọna, tobẹ ti aisan wẹwẹwẹ ti ki ṣai ṣe awọn ọmọ titun lẹhin wiwa'iye wọn, ko lagbara pupọ lori Iwe-Irohin "Eko Akete" yi, nigbati a ṣẹṣẹ nfi omi rọ ọ.

Ni sa yi a ri ninu awọn ọrẹ ti nwọn sọ fun ni pe nwọn ko ro pe işẹ na le m'ọyan lori, nitoripe nwọn sọ ni ero tiwọn pe, gbogbo enia kọ lo mọ Yoruba ka; şugbọn a dupẹ pe ero yi ko lẹşẹ nilẹ lẹhin igbati a bẹrẹ işẹ Iwe-irohin na, nitoripe a ri ọpọlọpọ ninu awọn oni şokoto gbọrọ ti nwọn ko ti nbikita ri fun ati ka ede wọn, ani Yoruba ni iwe, bi o tilẹ jẹ pe ede na ye wọn yekeyeke ni ọrọ sisọ ti nwọn si ti di ọga ninu mimọ ede na ni kete ti nwọn bẹrẹ si ngba "Eko Akete." Ki si şe eyi nikan, a tun ri bi meji tabi mẹta ninu awọn Iwe-Irohin ọsọsẹ wa ti a ntẹ ni ede Gẹsi ti nwọn si [illegible] wa jẹ nipa titẹ apakan Iwe-Irohin [illegible] ni Yoruba fun akoko kan; bẹ na si ni a nri iwe Wosika (*Letters*) gba l'ọtun l'osi nibi ati lati Idalẹ nipa ede Yoruba to jina ti awọn ọrẹ wa wọnyi njẹri si pe a fi nkọ "Eko Akete" Bẹ lo ri "Bi ... ba nşẹ gege ọtẹ, ki a mu ti Asẹhin kuro," bi a ba nsọ ti Iwe Irohin ti a nşe ni ede Yoruba larin wa nibi, ki işe bi ti Iwe Irohin-Oyinmọmọ ti o njẹ "Eko Akete."

Ko si ẹniti ko mọ pe işoro pupọ lo wa ninu ohun ti a ba şẹşẹ bẹrẹ: işoro ati ijaiya nipa ti owo lati ma fi ba işẹ na lọ eyi ko şai jẹ inira fun wa. Nigbati a bẹrẹ ti a si nba a bọ, loju awọn ẹlomiran ilu kovi koyi ko şubu ni nwọn nlu, irufẹ awọn bayi ni nwọn wa ni'po joko s'ẹnu mi ẹşin Liadi !!! Şugbọn a şọpẹ pe ọgọrọ awọn Sanmari ilẹ yi l'ọkunrin, l'obinrin, l'ọmọde, l'agba, ti nwọn ti sanwo asansilẹ ni gbigba "Eko Akete" ati diẹ ninu awọn onişowo ni dudu ni funfun ti nwọn si npolowo ọja sinu rẹ, awọn wọnyi lo wa nipo "Sogunro" ti Iwe-irohin na ko fi d'oku titi doni, sibẹ sibẹ a ri diẹ ninu awọn ẹni wa na ti nwọn fi owo asansilẹ wọn jafara ni fifi şọwọ si wa, a bẹ irufẹ awọn enia bẹ ki nwọn ma şai ji giri lati ŞURIGIDI BO WA.

A ni ireti pe gẹgẹ bi a ti nfẹ bẹrẹ işẹ ọdun keji l'ọsẹ t'o mbọ a o ri ogunlọgọ awọn ẹlomiran ti nwọn ti da wa da işẹ yi nikan latetekọşe. ti yio wa fi tayọtayọ ran wa lọwọ nipa pe ki nwọn ma gba a ati pe ki awọn onişowo tabi onişẹ ninu wọn le ma polowo owo tabi işẹ wọn sinu rẹ bakanna.

A şọpẹ lọwọ awọn aşoju wa (*Agents*) fi nwọn ti nba wa ta iwe yi nibi pupọ laigb'-okan, ati awọn to nra a ni ẹyọ ni ọsọsẹ.

A si tun dupẹ lọwọ awọn Ọkọwe (*Correspondents*) sinu iwe yi lati igbati a ti bẹrẹ rẹ titi fi di onioloni.

A ki nyin ẹnyin ara wa, Ẹ ku ara Ilu, Eko na a gbe olukuluku wa o ! ! !

## ṢAKI NṢE BI ỌRA, EGUN NṢE BI ẸRAN.

Ihin kan ni laipẹ yi pe lati Agege awọn Imale kan wa sọdọ Lemọmu Braimah l' Eko nibi lati sọ fun u pe nwọn nfẹ fi ẹnikan jẹ 'Oye Seriki Musulumi fun gbogbo awọn Imale Agege, nwọn tilẹ gboju gboya darukọ ẹnikan ti nwọn fẹ fun ni iru ipo bẹ. Ṣugbọn a gbọ pe Lemamu koiti fesi kọ̀kan bukun bofa. A mọ orukọ ẹniti o nṣakitiyan ọran yi, a si mọ orukọ ẹniti oluwarẹ nfẹ fi jẹ oye na ; a gbọ pe t' ọtun t' osi wọn ko mọ tẹtẹ ninu kewu, boya ni wọn tilẹ mọ " Fatiha " ke daradara.

A ṣe kilọ kilọ yi fun awọn enia wọnyi pe ki ẹsọ ko to wọn ni Agege nitori ọrọ yi, nibo ni nwọn wa ti nwọn ranṣẹ s' ara 'le ? Oju kan l' ada nni : nwọn ni lati mọ pe, Seriki Musulumi kan na to wa l' Eko on kanna lo si wa fun gbogbo Igberiko Agege ati ibomiran ti ko jina sibi.

Ti irufẹ awọn ẹni bẹ ba fẹ joye ki nwọn mura ati lọ joye Ẹlẹmu lọna Iwaiya ! ! !

*Ed*—" EKO AKETE."

## *Open Letters.*

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DEFFERENT WALKS OF LIFE.

No. 25.

To CAPTAIN H. W. R. ARMSTRONG, M.C.
Commissioner of Police.
Colony, Police Force.

Gallant Captain,

It is stated on good authority that an Application for a Pass lately submitted to your Force by some person or persons in town, for drumming anent the funeral obsequies of a man by the name of Longe, a noted Native Doctor of his Guild, who died not long ago at his residence, Lafiaji, Lagos, was refused by the Police on the ground that drumming is prohibited in certain part or parts of that vicinity.

So far as I know, this neighbourhood has not been declared a judicial area by the "Powers that be" where no noise is generally always unwelcomed, especially during the adjudication of cases, and perhaps the only reason which can be asserted, to my knowledge, is that the Application was refused principally because the residence of a high-placed Police Officer is situate thereabouts.

If this is so, then in my opinion, a refusal such as this certainly lacks that SYMPATHY which one expects to see displayed by an average Peace Officer towards those under the protection of His Majesty the King. Others hearing of this incident and the circumstances surrounding it, may not unnaturally characterise the whole show as ABUSE OF OFFICIAL POWER, and so it seems.

The public, sir, will hear of this happening with much regret, particularly, when it is known that "A little Sympathy goes a long way in this world."

Would you mind doing your best to guide against the recurrence of the act in future ? I trust your good sense.

EKO AKETE.

## IFESI SI IWE TI LỌYA E. J. ALEX TAYLOR KỌ NIPA OHUN TI A WI LORI IDAJỌ TI A ṢE LARIN IJỌBA ATI OLUDEMI.

III.

A YI I SI EDE YORUBA LATI INU *Nigerian Law Journal* TI OṢU APRIL, 1923.

Ki o to di pe Ọgbẹni Taylor lọ si Abọẹkuta, o ha jẹ sọ pe on ko mọ tabi on ko gbọ pe awọn ti o fun on ni ẹjọ ṣe nlọ ba ẹnikan fi ori ba ori wo, ẹniti o jẹ pe o lokiki, o lọla ati orukọ rere bi awọn na ti ni ; ẹniti nwọn mọ dajudaju pe o da duro gedegbe ni, ẹniti ko fori mulẹ labẹ ẹnikẹni bi awọn, bi o tilẹ jẹ talaka ko dabi akọwe tabi iranṣẹ.

Lori ọgbọn bi ede ofin ni a ṣe da Oludemi lare ni ? tabi nitori otitọ gan ti o farahan si awọn Kotu ?

A fi Oludemi sun gẹgẹ bi Ori Iwe 438 ti Ofin Ọdaran (*Criminal Code*) Bi ẹsẹ iwe na ti wi li eyi "Ẹnikẹni, iba jẹ akọwe tabi iranṣẹ, tabi adele akọwe, tabi adele iranṣẹ ti o ba ṣe ohunkohun ti o mu ọna itanjẹ lọwọ, eyini ni pe, ki o parun, (fi jona tabi ya) yipada tabi ki o ṣe makaruru iwe iṣiro owo, iwe kikọ tabi titẹ miran, ohun ti o lowo lori tabi iwe iṣiro owo ti o jẹ ti tabi ti o wa ni ikawọ ẹniti o gba a si iṣẹ o jẹbi iwa buburu ti o tobi, yio si wọ ẹwọn ọdun meje."

A le sọ pe ilo ofin dabi ẹroja, laisi rẹ nigba pupọ a dabi ẹnipe ẹnipe enia ko daran, a si jẹki nwọn fi ọdaran silẹ.

Enia le pe ẹjọ adohunmọ ki ọdun meji to pe, bi nwọn ba mu u wa lẹhin na, ẹniti o pe ẹjọ na le jare, ṣugbọn ẹniti a pe lẹjọ ni yio jare. A ko le pe ọlọpa l'ẹjọ fun ohunkohun ti o ba ṣe l'opopo iṣẹ rẹ afi bi o ba to oṣu kan lẹhin ti a ba ti pe e lẹjọ, ti a si sọ ohun ti o ṣe ki a to pe e lẹjọ, orukọ ẹniti o pe e lẹjọ ati ibiti o ngbe ati oruko Lọya rẹ pẹlu. Bi o tilẹ pe e l' ẹjọ na ti o digbati nwọn nrojọ ti ẹniti o pe ẹjọ ko le ro tirẹ ni aroyeni, ọlọpa na niyio jare rẹ. Awọn apẹrẹ wọnyi fihan wa gbangba ohun ti a npe ni ọgbọn ede ofin, (*technical ground*) afi awọn Lọya ti a kọ daradara nikan li o le mọ ọ.

*Koi ti pari.*

IGBẸ L' OWO WÀ

LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja *( Produce )* l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya ( Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra ( Lagos Stores )
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.

£16—£16 10 fun *ton* kan

EPO.

£25—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£27—28 fun *ton* kan bakanna.

KANO—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—£14 10 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

## *POSI T'O JIRE.*

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọṣọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si :—

Ọgbẹni HUDSON COLE,
P.O. Box 477,
Eko.


## *MR. A. KESSLER,*

7, LABINJỌ LANE, WILLIAMS STREET, LAGOS.

## Pilsener Beer! Pilsener Beer!!

*One's thirst is quenched on taking a glassful*

"LION BREWERY BRAND"

**Reduced to 32/- per case.**

*A TRIAL, FRIEND.*

Ọgbẹni na ni Ọti *Beer* tò yo-lù-wá ni tita ṣile mejilelọgbọn pere ni fun Apoti kọkan. Igbadun mbẹ nibẹ ẹ jare. Ẹ rẹ tọ wò.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No, L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onisowo to nranṣẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa. O si ma nfi ọja ṣọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranṣẹ ni wọnyi :—
Gọdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo, Obi, Igi Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranṣẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aṣọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oṣiṣẹ wa ko le ṣe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oṣiṣẹ ilẹ wa ko le se iru rẹ.



... ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki iṣe ti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi ṣe tabi eyiti o jẹ onidẹ (Brass)

Ẹ kọ ve tabitki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranṣẹ si nyin nibikibi ninu *Motor Transport.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

( MORNING )
Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ( Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | Rev. A. B. Akiẹle |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. Ransome Kuti |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | J. A. Lucas |
| 9 a.m. | St. John's ( Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. | St. Peter's ( Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. J. M. Akinloye |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity ( Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | |
| 7 p.m. | | |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | |
| 7 p.m. | | |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | |
| 7 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Erelu | |
| 7 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Bethel | Bro. A. A. Cole |
| 6.30 p.m. | | Rev. E. A. Akinọla |
| 9 a.m. | Zion | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Williams |
| 4.30 p.m. | | „ E. A. Amosu |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. O. Fadipẹ |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Araromi ( Baptist ) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | | Bro. John Apena |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. J. Tubi |
| 6.30 p.m. | „ J. Bandele |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Pastor, A. Adedeji Iṣọla |
| 7 p.m. | | do. |

( Special Sermons on Founder's Day

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣẹ ( Bamgboṣe Street. )

COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

Seservic at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread

7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service John P. A. Taylor, Wm. C. T. Terrel

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa.*

**N. V. Handlemattschappij V.H.**

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall,* (*Customs Street,*) EKO.





Awọn Oyinbo Oniṣowo yi nranṣẹ MASINI-ARANṢO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 f' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.


"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.


**Sorinolu's Grammar School.**

*The first ever Established in Abeokuta and Ijebu-Ode since 17 years ago.)*

All Grammar School Lesson efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fess Rated by the Readers :—*

Primers I and II—3/- *per Quarter.*
Readers I to III—3/- *per Quarter.*
Readers IV and V—6/- *per Quarter.*
Classes I to III—9/- *per Quater.*
Boarding Fee—£1 2s 6d. Monthly.

This is beside the Tuition Fee; and includes Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services

PLEASE NOTE!

Payments strictly in advance; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYỌ ṢORINOLU,

Iporo Ake, Abẹokuta. *Principal & Proprietor.*

**The Philharmonic Band.**



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY,*
c/o Aafani Motors
The Marina Lagos.

**JACOB A. AJAYI,**

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWỌ."

Awọ ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yo, ati Awọ Hausa ni orișirisi awọ, yala ni pupa, funfun, dudu, ofefe, ati orisi awọ miran ni a nta ni ọpọku ọyọku.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kọwe ṣọwọ pẹlu owosi:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*.—Alawọbata, EKO.

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYE

Fun Ile Ẹko.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sa kan nitori ogun German, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba da a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ oluko awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

---

## DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWE" SEWING INSTITUTE,

119, Tokunbọ Street, Lagos.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

---

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, Tokunbọ Street, Lagos.

Mrs. Frances Adeyemi Thorpe (Nee Green) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orișirisi ko ni egbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ni i.

Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.